i Stationary
"W BENCH"
Sinijoko irin t'o ula Ayedu, Iroko ati bẹẹ-lo ti lagbara to bẹ lo de'po ti a le gbe kakiri
Eo ri ra m.
LEVENTIS MOTORS LIMITED
(Technical Dept.)
Ebute-metta, Ibadan, Kano, Aba ati Port Harcourt

ELETI ỌFẸ
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

**Akiyesi Pataki**

A nfe aṣoju lati awọn ilu owọnyi lati ma ta Iwe Irohin Eleti - Ọfẹ ati lati ma ṣe aṣoju wa nibi gbogbo ti nkan atata ba ṣẹlẹ: bi Ife Ijebu Ode Ilesha Osi Oke-Ọdẹ Ajaṣẹ - Ipo Omu Aran Ilorin Ọffa Edẹ Ondo Owọ ati Akure.
OLOTU

OL. X No. 589. LAGOS, SATURDAY, SEPTEMBER 13, — SEPTEMBER 19, 1958 KỌBỌ MEJI (2d).

# ỌMO NIGERIA MEFA W'EWON NILU OYINBO

LONDON. Iru ewe taba kan ti awọn Oyinbo npe ni Indian Hemp, ti awọn sọ wipe mimu iru ewe taba bẹ ko le mu anfani wa fun ẹda enia.

Iru ewe taba na ni awọn enia dudu kan to ko ara wọn jọ nmu ki ọlọpa to ba wọn lẹnu rẹ. Orukọ awọn Amugbo na niwọnyi. Samuel Kofi, ti o nṣe Alaru Bode, wọ ẹwọn oṣu mẹfa.

Jonathan Jeh, Akun-ọda, Laguda Sọlomọn ti ko niṣẹ kan, Billy Omu Sọlankẹ, Akọrin ati Tẹsi Bello, ti o nṣe iṣẹ Welder, ẹnikọkan wọn oṣu mẹta-mẹta.

Angus Ade Baṣorun, Akọrin ati Clark Okoro ti ko niṣẹ kan, ẹwọn oṣu meji-meji. Eyiti nwọn pe ni Brown lo kigbe bayi pe, nwọn kan ju on si ẹwọn lori asan, ki nwọn wo oju on daradara.

Bẹni adajọ ra gbogbo wọn mọ ẹwọn nitoripe nwọn ka wọn mọ́ibi ti nwọn nmu ewe taba igbo na.

## Egbe Afenifere Se Ipade Nilu Jos.

JOS. Okiki kan nigbati ọlọ... Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, olori ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) ati Alakoso ijọba Iwọ-orun (Premier) de ilu Jos, ti ogunlọgọ awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ wa pade rẹ nibi ọkọ Ofurufu.



Oloye Awolọwọ ba awọn enia sọrọ pupọ, o ... han wọn wipe ọrọ ti iberu awọn ilu kekeke ti awọn...

(Wo yoku loju ewe kejọ)

## Igbimo Alakoso Oko Ofurufu Ti Nigeria Se Ipade Kini

ẸKO. Awọn igbimọ Alakoso ọkọ Ofurufu ti Nigeria ṣe ipade akọkọ ni ọjọ kewa oṣu yi, ...



a si gbọ wipe gbogbo ero ngba wọn l'o dọgba. Iṣẹ Ọkọ ofurufu ti awa enia Nigeria nihin yio bẹrẹ ni ọjọ kini osu October 1958.

Orukọ awọn Alakoso (Directors) ọkọ Ofurufu na niwọnyi:- Ọgbẹni R.W. C Baker-Beal, Alaga Igbimọ, Oloye S.L. Edu, Ọgbẹni A. O Ene, Mallam Sule Katagum, Brg. P.J.D. Toosey, Ọgbẹni L.E.T Evans ati Sir George Cribbett, nwọn ṣe ipade igbimọ Alakoso na ni ile iṣẹ Ọkọ Ofurufu ni Ikeja.

### ẸNITI O ṢE OWO AIYEDERU WỌ ẸWỌN

ZARIA. Ọdọmọkunrin Hausa kan ni ọlọpa gbọ ... hin rẹ pe o nṣe owo. ... ọlọpa si gba iwe aṣẹ lati lọ fi iwe ipa tu ibugbe rẹ wo.

Ọkunrin na ni Uṣuman Dandodo, nigbati awọn Ọlọpa yẹ ile rẹ wo, nwọn ri ẹrọ ti nwọn fi nṣe ati owo aiyederu ti o pọ to Pọun meji ati ṣile marun.

Adajọ bere bi o jẹbi tabi ko jẹbi, o si dahun pe bẹni on jẹbi lo ba lọ gbẹwa oṣu mefa.

# Oba Kano Tun Nlo Silu Oyinbo



Ninu awọn enia ti o nlọ silu Oyinbo lati lọ gba ominira bọ wa ni Malam Sanusi, Emir tabi Ọba igboro ilu Kano. On pẹlu ọmọ rẹ Alhadji Baba ti o ngba ọwọ lọwọ Lennox Boyd ti o nṣe Sekiteri agba nilu Oyinbo, ni a nwo ninu aweran yi.

A gbọ wipe ọba ilẹ Katṣina yio lọ ṣe aṣoju fun igbimọ awọn ọba ilẹ Hausa pẹlu.

## Anikan Da Ggbe'le Ko Dara

ENUGU. Irohin ti a ri gbọ lati ilu Enugu, ilẹ awọn Ibo ni wipe obinrin kan ti nṣe nikan ndagbe inu iyara rẹ ninu ile wọn ni ẹniti o ti ku sinu iyara rẹ ti ẹnikan ko mọ, ayafi igbati ọkan ninu awọn oniṣẹ ọba (Postman) mu iwe wa fun obinrin na ti nwọn ko ri ninu iyara, ni awọn alabagbele rẹ fi agbara ṣi ilẹkun mọ lori ni nwọn si ba oku rẹ lori ibusun to ti gun.

Awọn Yoruba ti nwọn mu nsọ wipe "ẹnikan l'oku ko parọ rara", nitoripe bi ko ba si ti ẹniti o nfi iwe wa obinrin na, iba ferẹ to ọjọ keta ki nwọn to mọ wipe o ti ku sinu iyara rẹ.

## Ejo Apania Ilu Abakalike

ABAKALEKE — Gbangba d'ẹkun kedere bẹwo ni ejọ awọn apania ti nwọn bẹrẹ si riro ninu Kotu Asaisi nilu Abakaliki, ilẹ awọn Ibo

Ẹlẹri kan sọ wipe on ni ẹniti Oloye awọn ti o njẹ Idika Igboji yan lati gba owo jọ lati le fi juwọ silẹ fun Ọlọpa ti o ba wa ṣe ofintoto iwadi iwa ati iṣe awọn ẹgbẹ Odozi Obodo ati Ezepute. On si ri owo bi Pọun mẹrindinladorin gba.

Ẹlẹri keji sọ wipe Oloye awọnyi jẹ ẹnikan ti o ma nsọ wipe ki awọn da owo jorekore. O sọ wipe o tilẹ bu pọun mẹwa fun on ni aisan lati lọ fi ṣe ọlọjọjọ awọn Ọlọpa to ba wa ṣe iwadi ...

... sọ wipe awọn ẹgbẹ ...pute ni awọn jandaku enia ti Oloye na nyan lati pa enia ti a ba mu fun ole jija pẹlu awọn Bẹṣikula. Ati pe gẹgẹbi on ti jẹ ọkan ninu ẹgbẹ Odozi Obodo on ni ẹni pataki ti Oloye yan lati ma fi awọn ọmọ ẹgbẹ bura tabi mu'lẹ.

(Koiti pari).

## AW'ENIBAKU OLOMOLANKE

THE CARELESS OMOLANKE AND IMPATIENT DRIVER




Ọlọmọlanke kan ti ko bikita fun ofin oju ọna mọto, kaka ki o rin si apa osi, apa ọtun lo nrin si. Bẹni mọto kan yọ ni okere ti o mbọ, sibẹ Ọlọmọlanke yi ko kuro loju ọna. Onimọto yi ṣẹ ko ni suru, lo ba talu onimọto. Ẹọ ri onikẹkẹ ti o nlọ jẹjẹ ara rẹ ti o lọ ku iku afojuri Ọlọmọlanke nilọ

## Ogedengbe Macaulay Da Egbe Kan Sile Nilu Oyinbo

LONDON. Awọn ọmọ Ilẹ Nigeria ti o mbẹ ni ilu Oyinbo da ẹgbẹ kan silẹ nilu London, orukọ ẹgbẹ na njẹ Nigerian Rehabilitation Committee.

Awọn ti o jẹ ogunna gbongbo ninu ẹgbẹ na ni Ọgbẹni Ogedengbe ọmọ Ologbe Herbert Macaulay ati Tunde ọmọ Alakija. A gbọ wipe awọn ọmọ ẹgbẹ yi ti ngbaradi lati gbe orukọ ẹgbẹ yi jade si awọn Minister ilẹ Nigeria nigbati nwọn ba wa sọrọ nipa ominira ilẹ wa oti lati se alaye iru iṣẹ ti ẹgbẹ na fẹ lati ma ṣe.

Diẹ ninu iṣẹ ti ẹgbẹ na fẹ lati ma ṣe ni, lati ma se iranlọwọ fun ọmọ ilẹ Nigeria ti o ba gbin torọ silu Oyinbo, tabi eyiti o nfẹ iranlọwọ nitori ti o ṣe alaini. Awọn ti ara rẹ le, ṣugbọn ti o nfẹ iṣẹ ti ko ri, ẹgbẹ yi yio ba oluwarẹ wa iṣẹ ti yio ma ṣe.

Ẹgbẹ yi yio si ma fi imu finlẹ kakiri London bi a ba ri eyiti o mọ iṣẹ ribi-ribi ti o si le ṣe anfani fun ilẹ Nigeria ao fi ranṣẹ silẹ, ati bẹbẹ kakiri.

## Igbimo Alabojuto Ko le yo Alaga

**ILỌRIN. Ọgbẹni J. S. Ọlawọyin ba igbimọ Alabojuto ilu Ilọrin fa akatakiti lori ero ti igbimọ na gba wipe ki nwọn yọ Malam Sule Maito kuro ni Alaga igbimọ Ijọba ibile Ilọrin.**

**O sọ nilu Kaduna wipe ẹgbẹ Talaka Parapọ lo ṣi pọju ninu igbimọ Alabojuto ti Ilọrin, ẹnikan ko si le jagun ki o tayọ eyi ti a nṣe yi.**

**A ko gbọ ri wipe awọn enia ti ko pọ npaṣẹ fun awọn ti o pọ. Ọgbẹni Ọlawọyin ti lọ ke si Malam Abdulai Meikano Dutse, ti o nṣe Minister of Local Government lati ba wa mojuto aiyederu na.**

**Ninu igbimọ Town Council Ilọrin ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ti o wa nibẹ jẹ, 28 ọmọ ẹgbẹ Olomi jẹ 23.**

## Aboyun Kan S'onu Nilu Enugu.

Ọdomobinrin kan ti ko ju ọmọ odun merinla lo ti o si loyun sinu ni awon enia re fi se awati nilu **Enugu.**

Awon enia re sare lo rohin fun olopa, **obinrin kan ti o** nje Okoro eniti obinrin ti o sonu na ngbe odo re **so fun** awon Olopa wipe, o ti iwon osu kan nisisiyi ti on **ti ri** aboyun na gbehin.


**Igbadun wa ninu**

**Ọti Heineken's**




*Orun didun pẹlu agbara lo sọ*

**Ọti Heineken's**

*di ọba gbogbo awọn ọti*

# ELETI - OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI L'ẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRA

28, Kosoko Street, Lagos "ELETI - OFẸ LAGOS"

P. O Box 467 Phone 23370

VOL. NO. X. 589 LAGOS, SATURDAY SEPT. 13 - 19 1958.


## Eje K'a Moju Aje Kan Oniso

Kosi orin ti a le kọ si gbẹdu afi ero ya wa wo. Awọn oluwadi ti o wa ṣe iwadi iberu awọn ilu kekeke nilẹ Nigeria ti fi konko le ori ọrọ ilu Ilọrin ati Kabba ti awọn enia ilu na nfẹ pada sarin ẹbi ati iyekan wọn nilẹ Iwọ - orun. Ki iṣe wipe awọn ilu wọnyi nfẹ ṣile ṣi ọna kur ibiti nwọn gbe do si yugbọn ki Ijọba Ariwa mu ọwọ kuro lara wọn ki awọn le fi ara mọ iṣe ati iiosi awọn iran wọn ti nwọn jẹ Yoruba nilẹ Iwọ - orun.

Awọn oluwadi fi oke le wipe bi awọn olugbimọ ti o nlọ ṣe eto ilu wa nilu Oyinbo ba de ọhun, ti nwọn ba fi ohun ṣọkan wipe ki a dibo lati fi yanju ọrọ awọn ilu Ilọrin ati Kabba nitiripe o ti han gedegbe fun enikẹni wipe awọn enia ti o nfẹ pọ pupọ ju awọn ti o jẹ pe aye ipo wọn ti nwọn wa ni ko jẹ ki awọn enia diẹ na le jade otitọ.

Bi nwọn ba dibo lati fi jẹri mọ awọn enia ti nwọn nfẹ papọ mọ ilẹ Yoruba nilẹ Iwọ - orun gẹgẹbi awọn ti pọ to, ati awọn ti ko fẹ, o da awa Eleti-Ọfẹ loju wipe ago ni yio de adiẹ pirapira. Eyi ni yio fihan pe tulasi ni Ijọba Ariwa fi nlo awọn ilu na.

## Imoran Fun Enyin Abiyamo


Enyin Abiyamọ ẹ wa ra ỌMỌRẸLA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama jẹ ki ọmọde ri orun sun daradara o dara fun ọtutu, ikọ ati oriṣiriṣi arun miran ti o ma mba ọmọ ja ni asiko ehin. Ọpọlọpọ abiyamọ lo ti lo egbogi yi fun ọmọ wọn ti wọn si sọ wipe o dara pupọ fun awọn ọmọde

ỌMỌRẸLA BABY MIXTURE

(Ṣile Meji Abọ 2/6d Fun Igo Kan)

O wa Lọdọ

COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemists)
10, VICTORIA STREET, LAGOS.


## Omo Akeko Nilu Oyinbo



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni ọmọ ilu Shagamu kan nilẹ Ijẹbu ti orukọ rẹ njẹ, O.T. Adedoyin, on lo lọ kọ iṣẹ ẹrọ isọrọ ofurufu labẹ awọn oyinbo kan ti o nṣe owo ẹrọ isọrọ ti ofurufu. Ẹniti o duro lọwọ ọtun ni O.T. Adedoyin eyiti o wa ni ọwọ osi ti o bẹrẹ ni Ọgbẹni L.D. Adams olukọ agba.

## Igbakeji Alase Igbimo Nilu Oyinbo



Ninu awọn enia merinle-logun ti o lọ ba wọn ṣe ipade karun ti awọn olugbimọ ti a ṣe nilu Oyinbo ni Mallam Bello Dandogo, igbakeji Alase de Igbimọ Agọgọ ati akọwe ile igbimọ Ọgbẹni D.C. Igwe wa. Awọn ni Ọgbẹni L.W. Bear, Olotu Iwe Iroyin Ijọba ti nwọn npe ni "Hansard" mba sọrọ ninu Ile igbimọ, (House of Commons) ti a nwo ninu aworan yi.




# Ko Si Eniti Kole Se Asise

TOKIYO. Awon ijoba ilẹ Japan ṣe ofin kan le ori awọn Bale (Father) l'u na gegebi ati gọọ bẹyi pe :-

Ko yẹ ki a ma ba awọn Bale nibi ohun asan ile aiye. Awọn Bale ko yẹ ni ẹniti yio ma jowu. Nwọn ni lati ni oju nanu. Nwọn ni lati mọ kini ohun ti o mbẹ ni ọkan ọmọ wọn, nwọn ko tọ si ẹniti yio ma huwa omugọ, nwọn ni lati ma mu ileri wọn ṣẹ. Ko si tọ si-wọn lati ma fun awọn enia wọn ni owo abẹtẹlẹ.

Nigbati iwe yi jade, ni-gbogbo awọn Padi ti ijọ Aguda ilẹ Japan ba sopan-pa, ti nwọn kigbe lọ ka awọn Ọlọpa mọle ni adugbo kan ti nwọn npe ni Kabara ti gbogbo nwọn nho ge-e. Nigbati nwọn ko jẹki awọn ọlọpa simi, ni nwọn bere pantiwa lọwọ wọn ?

Nwọn dahun pe, Eṣe ti nwọn fi ka gbogbo ọrọ wọnyi mọ wọn lọrun tan ? Padi ki iṣe Ọlọrun ko si si padi kan ti ọwọ rẹ mọ kuro ninu gbogbo ẹsun ti a ka silẹ yi ayafi Pope nilu Rome.

Bi nwọn ti nsọrọ yi, a gbọ pe bẹni nwọn ngbe asia wa si oke, lara eyiti nwọn kọ ọrọ si wipe, "Ko si ẹniti ko le ṣe aṣiṣe". Ṣugbọn Ijọba sọ fun wọn pe Father ti awọn . arukọ sinu ofin na, ki iṣe Father ti ijọ Aguda, Father ti Bale ile ni awọn wi.

# Ija Ko Nbimo To Ro

KANO. A gbọ wipe enia meji ba ara wọn ja nilu yi tobẹ ti ọkan ni lati tẹri gba asọ eyiti koku ni adejọ sọ fun wipe o jẹbi ẹsun aimọmọ pa enia nitorina ki o lọ fi ara gba ọgọrun bulala.

Bi a ti gbọ ti ọrọ na lọ niyi, ẹnikini dide lọ sin ẹnikeji ni gbese ṣile meji abọ, nibiti awọn mejeji nfa ọrọ na mọ ara wọn lọwọ, ibẹ lo ti dija, ni ọkan ninu wọn ba fo ṣanlẹ, o si ku.

Adajọ sọ wipe, Dokita to juri oku ọmọ ti o ku na sọ wipe, ija ti awọn mejeji ja lo ṣe oniko iku ọmọ na, Nitorina on ri wipe ọdaran na jẹbi ọgọrun Bulala lẹhin Bulala ki o wa lọ gbẹwa ọdun kan lọgba ẹwọn.

# Enia Dudu Lo Ko Ise Ona Moto Nile Amerika

**A gbo irohin wipe omokunrin kan ti nwon npe ni S. B. Audiferen ti o nse ise Engineer labe P.W.D. nilu Eko ni nwon fun ni aye ilosiwaju ninu eko olofe lati lo ko gegebi awon ara ile Amerika ti nmo-juto ona moto won.**

**Bi o ba de ile Amerika ibiti yio gbe lo ko ise na ni Purdue University.**

**Awon alase oju ona moto ti ilu Eko lo fun ni aye na. Iyen wu wa o.**

# Dr. Olorun - Nimbe Gba Owo ISe Re



EKO. Dr. Olorun-Nimbe ni eniti o koko je oye Mayor nilu Eko. o si je oye na ni ọdun 1951 si 1952 t ko si tẹwọ gba epinni, kọbọ aladọjọ fun iṣẹ ti o ṣe na.

A gbọ wipe Dokita yi ni Aṣiwaju ẹgbẹ Nigerian National Democratic Party ti o jẹ alabaṣepọ pẹlu ẹgbẹ N.C.N.C. ni asiko na.



GOMINA MACPHERSON

Nwọn ṣe igbimọ lori iye owo ti nwọn o ma san fun Mayor Eko, nwọn ṣọnu pe, ki nwọn ma fun Mayor ni ẹlegbẹta lelegbaa Poun (£2,500) ni ọdun kan. [illegible] ọmọ ẹgbẹ Area Council [illegible] pẹlu ẹgbẹ Afenifere [illegible] owo na ti pọju, nwọn si [illegible] [illegible] ọrọ nwọn lọ s'waju Gomina Macpherson fun 'ayẹwo.

Gomina yi wa damọran wipe iye owo ti igbimọ Town Council fẹ lati ma san fun Mayor na ti pọ ju, ki nwọn ma fun ni ẹgbẹrin Poun (£800). A gbọ pe Mayor kọ, awọn alatilẹhin rẹ papa si kọ, eyi ni ko jẹki o tẹwọ gba owo titi to fi l'aye na silẹ.

Lọdunni ni awọn igbimọ Town Council gbimọ pọ lati san owo ọdun meji, ẹgbẹta-lelẹ-berun Poun (£1,600) pada fun Dr. Olorun-Nimbe. Inu Ijọba dun nitori ti Dokita na fi tayọ-tayọ gba owo na.

# Oro Alafin Koiti Pari

OYỌ. Nigbati Oloye P.A. Afọlabi, ọkan ninu awọn aṣiwaju ẹgbẹ N.C.N.C. lode Oyọ fi mba awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ sọrọ, o sọ pe ki ẹnikan maṣe rope, ibẹ yẹn ni ọrọ ti Alafin pari si, ati wipe kuta-kuta ija ọlẹ pin, Kara! ẹ maṣe ni ero bawọnni. Mimisẹhin ti ẹran agbo, ko nṣe ti ojo- Ki awọn to fi aiye silẹ awọn nigbagbọ pe Alafin Adeyẹmi ni lati pada sori oye rẹ.

Oloye na tun nfi ye awọn ẹmọlẹhin rẹ pe yiyọ ti nwọn yọ Alafin kuro lori oye ọba ko ni parẹ kuro ninu itan laelae, a si ti dawọle ohun ti ko tọ ki a ṣe eyiti ẹgbẹ Afenifere ko gbọ ọrọ ti Olorun wadi sọ ti nwọn si yi pada.

Otan sọ pe Ẹgbẹ Afenifẹre tun lọ ko wahala ba awọn ara ilẹ Hausa. Nitorina on fi eyiyi ke si enyin igbimọ wipe, nigbati ẹ ba de ọhun ki nwọn maṣe tako Dr. Azikiwe. ni ilu London.

# Lemomu Epe D'ologbe

ẸPẸ. A gbọ irohin iku Alufa Abudu Lasisi Gbagọ, Lemọmu Jamiyu, ilu Ẹpẹ, o ṣe alaisi ninu ile rẹ ni ọjọ kọkanlelọgbọn osu August, nwọn si ṣe isinku rẹ ni ọjọ kini oṣu September 1958.

Ẹṣẹ gbogbo awọn Lemọmu Ratibi ati awọn Alfa pataki - pataki lo pe sibẹ, awọn Alhajaji ati awọn gbajumọ, bọrọkini enia pe sibẹ - pẹlu. Awọn Oloye Edu, Ọlọla Tobun., Ọgbẹni O. V. Young ati Alhaji KAKA pẹlu awọn ti ako le darukọ tan l'o fi ọla wọn bukun isinku Lemọmu na.

(Wo yoku loju ewe keje)

Bi Iwo Ba Fe Je'Gbadun
Ra Siga BICYCLE
Ti O L'okiki Nile Nigeria




## Kere o !

Ati ni orisirisi ogun German to ṣe de, fun oniruru aisan tokantokan tobintobin. Tete wa ra tire kio to tan.

J. A. AJAO
BROTHERS
MEDICINE STORES
7, Egerton Road Lagos

## Emi Mimo Yato Si Olutunu

OLOTU. Jọwọ gba mi laye lati ṣe alaye yi fun awọn Kiriyo. Ninu iwe Joel 2. 28-29, Ẹmi Mimọ ti Woli na ṣe apejuwe rẹ yatọ si eyiti awọn Kiriyo kọ sinu Bibeli wọn John 16, 5 - 13.

Lati fi han wipe Anọbi Muhamad ni olatunu ti nwọn sọ pe o mbọ na wo iwe Kurani Mimọ 7.157-158.

Ṣugbọn emi ko gbagbọ pe ẹmi mimọ lo njẹki enia riran. Bi Kiriyo ti nriran, bẹni awọn Imale nri pẹlu awọn Onibori Hausa nri i, bẹni awọn Aborisa nri i, pẹlu.

A gbọ wipe nigbati ẹmi na ba le awọn ọmọ ẹhin Jesu, awọn ti ko gbọ ede Rome nsọ ọ, omiran nsọ Griki, omiran Heberu, a ko si gbọ pe nwọn gbagbe ede yi.

Awọn ti a gbọ pe ẹmi yi ba le ni akoko yi, nwọn ko gbọ Hausa de ipo ti nwọn o sọ Tapa Ẹyẹ ara nyiu wo.

Lemomu Ajakuta

## Ijagboro Sele Ni Bornu

BORNU Irohin de ọdọ wa wipe gẹgẹbi awọn ọjọgbọn ti nṣẹtu si ọrọ ilẹ Bornu yi to, sibẹ sibẹ, ijagboro bẹ silẹ larin ẹgbẹ N.P.C. ati Bornu Youth Movement.

Malam Ibrahim Imam, ti o nṣe aṣiwaju ẹgbẹ awọn Bornu Youth Movement rohin bayi wipe :-

Ni oru ọjọ Sunday nigbati on njẹun lọwọ, ni on kan dede ri awọn janduku enia rọọe ti nwọn si rọgba yi ile on ka nibi ija na ni ọkan ku ninu ọmọ ẹgbẹ N. P. C.

On ṣe akiyesi wipe mọtọ N.PC. kan lo ko awọn janduku na wa laisi ikilọ tẹlẹtẹlẹ. Gbogbo ferese ati ilẹkun on ni nwọn ba jẹ kalẹ. Ọmọ ẹgbẹ Bornu Youth Movement meji ni nwọn lu pa, orukọ wọn ni Tafa ati Makinta.

Nigbati nwọn kuro ni ile Malam Ibrahim Imam, nwọn tun kọri si ile ọmọ ẹgbẹ Youth Movement miran ti nwọn mọ, nwọn tun pa ọmọ ẹgbẹ Bornu Youth Movement meji orukọ wọn ni Malam Masta ati Malam Mustafa ninu ile awọn enia meji nwọnyi ni nwọn lu wọn pa si.

## Lemomu Epe D'ologbe

(O bẹrẹ loju ewe kẹfa)

Ẹniti a gbọ wipe awọn enia tun nromi royẹfun le lori pe on ni yio jẹ oye Lemọmu rọ'po Alfa Abudu Lasisi Gbagọ to fi aiye sile na ni Alfa Nọsiru ti O jẹ Ẹkẹta Adini ilu Ẹpẹ.

## Akojo Egbe Omobinrin Girl Guides



Ninu ipade nla kan ti gbogbo awọn Girl Guides ti o mbẹ ni gbogbo agbaiye ṣe ni italẹju ode goangoa windsor Great Park orisirisi awọn Guides lati orisirisi ilu we lo jijọ ngbe nlu ago kan na.

Ninu aworan ti a nwo yi ni awọn girl Guides mẹrin. wa orukọ wọn nwọnyi lati ọwọ osi Ade Lawal ọmọ ilẹ Nigeria lo wọ aṣọ dudu ti o sun le ori tabili ti o nkọwe ile lati jihin iru ere ti nwọn ṣe fun awọn obi rẹ. Marion Canning ara ilu Wales lo wa lọtun. Sylvia Davies lo nfi iwe kan han ẹnikeji rẹ Gascoyne ara ilẹ Nigeria.

## Awon Iko Ti O Nlo Silu Oyinbo



Awọn ti a nwo ninu aworan yi ni awọn Ikọ ilẹ Nigeria ti nwọn nlọ silu oyinbo lati gba ominira bọ wa silẹ Orukọ wọn nwọnyi lati ọwọ osi, Mallam Ribadu Oloye C.D. Akran Alhaji Ahmed Sardauna Sokoto Oloye Awolọwọ ati Oloye F.R.A. Williams.


Talo si ile Yinyin na?

Emi ni, Bẹni Sammy Sparkle wi.

Asiko lo fun Oti STAR'

No. 113

# "Notice To All Employers"

The return of employment and earnings is called for each year in September under the provisions of Section 14 of the Labour Code Ordinance and also Section 14 of the Statistics Ordinance.

The enquiry will be conducted this year on the same lines as last year. The complete co-operation of all employers is necessary for the enquiry to be successfull. Employers are assured that information submitted will be treated as strictly confidential.

The forms, and full instructions regarding their completion, will start to be distributed in September. If any employer of 10 or more persons has not received the form by the end of September, he should immediately get in touch with one of the Labour Offices in the following places :-

Northern Region :- Kaduna, Kano, Jos, Ilorin Zaria.
Western Region :- Ibadan, Warri, Benin, Sapele, Akure Abeokuta.
Eastern Region :- Enugu, Calabar, Port Harcourt, Aba Abakaliki.
Southern Cameroons :- Buea.
Lagos :- Alakoro Marina.

Employers concerned are requested to complete and return the forms to the nearest Labour Office not later than the 20th of November, 1958.

# Egbe Afenifere Se Ipade Nilu Jos

(O bẹrẹ loju ewe kini)

oluwadi ti ṣe koiti pari, awọn yio ri pe a ṣe idasilẹ awọn ilu kekeke bi Middle Belt, Mid - West nilẹ Benin ati C. O. R. nilẹ Ibo, ki o to di ọjọ keji oṣu April ti ọdun 1960 nigbati a ba de ilu Oyinbo fun apero ti ominira.

Nipa imọran awọn enia atata ti nwọn wipe ki Alakoso ẹgbẹ Afẹnifere maṣe lọ silu Maiduguri ati Bauchi ni asiko ti awọn janduku enia nṣe ijọngbọn nibẹ yi, ni o ṣe sọ wipe on ko ni lọ sibẹ mọ. O si ba awọn Ogunna gbomgbo ọmọ ẹgbẹ rẹ sọrọ ki o to filu Jos silẹ.


ARA-O-LIN - IPARA ATATA




ARA-O-LIN jẹ ipara ti o gbamuṣe. O tayọ gbogbo irufẹ egbogi bẹẹ ti o ba l'ọja. O dara fun lakuregbe, ẹgbẹdidun, aranlatanlatan, ẹhin-didun, ibaradi-ṣiṣẹ, arinka-inu-egun idi apa tabi ẹsẹ rọ, efori, tulu, otutu-aiya, otutu-agbari, ikun-didimu, ọrun-didun ati orisirisi aisan kungẹkungẹ bawọnni. Nitori werewere ti o nta, awọn Yoruba npe e ni "ATA", Ibo npe e ni "OSE" Hausa si npe e ni "BORỌKỌNU". Dan igo kan wo ni 2s. 6d. (ọtọ l'owo-ọkọ) lati mọ bi o ti ri.Koṣemani ni.

**The Ẹgba Trading Aradan Stores,**
18 Denton Bridge St., P. O. Box 2, Ebute-Mẹtta.


# Awon Ti O Nlo Soju Ijoba Iwo Orun Nilu Oyinbo

IBADAN Awọn ti o jẹ ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre (A.G.) ti Ijọba Iwọ-orun yan lati lọ sọrọ nipa Ominira ilẹ Nigeria nilu oyinbo ati awọn ọmọ ẹgbẹ N.C.N.C. ati lati ilu Eko.

Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ni aṣiwaju ẹgbẹ Action Group ti o nlọ. Ẹniti o tun lọ ni Oloye F. R. A Williams, Agbẹjọro Ijọba Iwọ–orun Ọgbẹni Ayọ Rosiji, Alabojuto Ilera ilu A. O. Igbodaro, ati L.J. Dosunmu.

Awọn olumọran ti o mba wọn lọ mojuto ọrọ na lọhun ni Ọgbẹni Fani Kayọde, Reis Edukugho ati J.S. Ọlawọyin.

Awọn ti o nlọ ṣoju fun Igbimọ Lọbalọba ni Kabiyesi, Sir Adeṣoji Aderẹmi ọba Ọni Ile-ifẹ, ati Aladesanmi Ọba Ẹwi ni Ado Ekiti. Olumoran fun wọn ni Ọgbẹni S. O. Adebọ, Akọwe igbimọ Lọbalọba M. T De - Winton akọwe Ijọba Iwọ-orun.

Ọmọ ẹgbẹ N.C.N.C. ti o nlọ ni Osadebay, Olowofoyeku, Agbaje, Otobo ati Afolabi. Awọn enia ti o tun nlọ niwọnyi:- Oloye Orode, ilu Okpe Alhaji Gbadamọsi, Durosaro, Muphy, ati Iyafin Wuraọla Ẹsan. Awọn na jẹ ọmọ ẹgbẹ Afẹnifere (Action Group)

# Akiyesi Pataki

A ti eyi ... de fun ẹbẹgbo enyin ... Iro ... wa nilẹ Yoruba. Fake Ọya, nilẹ Ibo. Fake ... ati ... Oyinbo ... caikọ ti ko ba ... owo na r ... nṣẹ ki ẹṣu to pari ao ko orukọ rẹ fun Loya Eleti-Ọfẹ, ao ita ṣe ẹjọ ao ... gba owo ... ese ... lowo ... re

# Ejo Omoba Ifemenam Di Kotu Nla Asaisi

EKO. Ẹjọ ọmọba Mofunanya Ifẹmenam ti awọn ọlọpa fi sun ẹsun wipe o purọ wipe awọn enia kan npete - pero lati ṣe jamba fun Dokita Azikiwe, ẹsun keji ni wipe o tun purọ lọ ṣe ibura niwaju Olotu iwe ibura ti kọtu ọba.

Nigbati adajọ Kotu Ijọba Ọgbẹni J.A. Ṣomefun gbe ẹjọ na si Kotu Asaisi o sọ pe ẹri ti awọn to wa jeri jẹ ye koro, nitorina ọdaran yi yio lọ wi t'ẹnu rẹ fun adajọ Kotu nla, nibiti biriki gbe dun'lẹ.

Awọn enia pataki ti o wa jẹri ninu ẹjọ yi ni Dokita K.O. Mbadiwe, Oloye Kọla Balogun Ọgbẹni John Sullivan, ọga ọlọga Ọgbẹni H. Holder, Ọga awọn ọlọpọ, Ọgbẹni Ayọdele Kumuyi ati ọpọlọpọ awọn enia ti a ko le darukọ tan.

Adajọ gba iduro edẹgbẹta pọun fun ọmọba ọdaran na ati iye owo kanna fun enia kan ti yio duro ṣe agbanawọ fun ọdaran na.

# Oloye Okotie-Eboh Ti De Ilu Oyinbo.

LONDON A gbọ wipe Oloye Okotiẹ Eboh ba ọkọ ofurufu gunlẹ silu Oyinbo o ba awọn aṣoju ile owo sọrọ lohun ati kọle-kọle ti o ṣe ilana bi ao ti ṣe kọ Central Bank fun ilẹ Nigeria.

Bi o ba lo ọjọ meji pere nilu Oyinbo, yio kọja lọ silu Oyinbo yio kọja lọ silu Amẹrika lati ... awọn olowo sọrọ lati ya owo fun ilẹ wa. Lẹhinna yio kọja lọ silu Kanada, fun apero pẹlu awọn ijọ rẹ.

Oloye yi sọ wipe on fẹ ki owo ma san wọ ilẹ Nigeria, nitori ti a nfẹ owo fun lilo ni akoko yi lati fi kan Kerẹmi titun, ilẹ ti ao ma ko awọn ẹru to ba ọkọ de si, ati awọn ọkọ alagbara ti o nfi ọna han awọn ọkọ ti o nwọle wa.


"Rapid" NUT CRACKING MACHINE
Ẹrọ t'o nyara pa ekurọ ati iru eso bẹ bẹ ẹ.
Ẹ o ri ra ni
**LEVENTIS MOTORS LIMITED**
(Technical Dept)
Ebute-meta, Ibadan Kano, Aba ati Port Harcourt.


Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company 2... Street P.O. Box 45... Price ...